Bibeli fun awon omode



# Awon eni ti ko ni gbojege

Akosile lati owo: Edward Hughes

Ayaworan: Jonathan Hay
Alastair Paterson

Olu'lo: Mary-Anne S.

Atunmo ede: Oluwashina Oluwadimu

Alakoso: Bible for Children
www.M1914.org

©2023 Bible for Children, Inc.
Iwe ase: Oni ase lati se atunko tabi attune itan yi,
niwon igba ti o ko so di owo.

Oba Nabukadinesari ya ere wura n la kan, o je wura, lati ori de ese.  Boya oba ti gbagbe ala ti Olorun mu ki o la nipa pe ijoba wura re ko nispe titi. Boya o lero pe ti oun baya ere ti o je wura patapata, oro Olorun nipa ala naa ko ni se.



Okan lara awon iranse oba ka ase yii fun gbogbo eniyan "... E gbodo teriba ki e si sin ere wura ... enikeni ti ko wole ki o sin a o so si aarin ina ileru."




Gbogbo eniyan lo mu ase oba se, ayafi awon okunrin meta. Omo Heberu ni won Awon ni Sadiraki, Mesaki ati Abednego, awon ore Danieli, o dabi pe Danieli ko si nibe ni akoko yii, nitooto oun paapaa ko lati sin orisa atowoda eniyan.

Awon amoye oba n jowu Danieli ati awon ore re nitori pe oba feran won. Won wi pe awon okunrin meta kan wa ti iwo fi se alakoso lori ekun Babiloni – Sadiraki, Mesaki ati Abedinigo. Awon okunrin yii ko pa ase re mo oba. Won o sin olorun re tabi josin fun ere wura ti o gbe kale.





Inu bi oba Nebukadnesari. O ki won nilo, “Bi e ko ba josin, a o gbe yin so si aarin ina ileru. Olorun wo ni yio gba yin kuro lowo mi?”

Oba n se asise nla. O n pe Olorun alaye nija. Awon Okunrin Heberu meteeta mo pe o tako ofin Olorun lati sin ere. Won duro lori ese won, tori won gbekele Olorun, eru oba ko ba won.



Awon Okunrin meteeta yii ni igboya nipa dida oba lohun.  Won wi pe, “Olorun wa ti awa n sin le gba lowo, ina ileru, Bi bee ko, je ko di mimo fun, o oba, pe awa ko ni sin olorun ere wura ti iwo ya”.



Inu bi oba Nebukadnesari! O pase pe ki a tun ina gbigbona da si nigba meje si ju bi oti wa tele, sibe awon okunrin wonyi o gbojege.



Oba pase fun awon okunrin alagbara ninu ijoba re lati de Sadiraki, Mesaki ati Abeinigo ka a si so won sinu ina ileru ti o n jo.



Oru ina ileru gbona de bi pe o pa awon okunrin ti o gbe Sadiraki, Mesaki ati Abedinigo sinu re.



Oba n wo lati oke rere to jina si ina. O ri okunrin meta ti a gbe so saarin ina ti o n jo lalala. Sugbon ki se gbogbo ohun ti ori niyen.



Enu ya oba Nebukadinesari "se bi Okunrin meta ni a de ti a gbe so si aarin ina?" O beere lowo awon amugbalegbe re. "Beeni, won dalohun." O wi pe, "kiyesi!" "Woo! Mo ri okunrin merin ni titu, won n rin laarin ina, won o si ni ipalara, Eni kerin dabi omo Olorun!"



Bi o ti sunmo enu ona ina ileru, Oba kigbe “Sadiraki, Mesaki ati Abedinigo, iranse Olorun ti o ga ju, E jade wa!” Sadiraki, Mesaki ati Abedinigo jade lati inu ina ileru.



Gbogbo eniyan pejo lati wo ara awon Heberu meteeta. Won ripe ina ko pa won lara: Irun won ko jo, aso won o jona. Efin o tile run lara won.



Nigba ti oba ri ohun ti o sele, o huwa ologbon, O gbadura, “o wi pe olubukun ni Olorun Sadiraki, Mesaki, ati Abedinigo, eni ti o ran angeli re ti o gba awon iranse re ti o gbekele”.



Awon eni ti ko ni gbojege

Itan lati inu oro Olorun, Bibeli

lari ka ninu

Danieli ori keta

"Iwole oro re funwa ni imole."
Orin Dafidi Ori kokandinlogofa ese adoje

Opin

Itan Bibeli yii so fun wa nipa Olorun
iyanu wa t'oda wa ti osi fe ki amo ohun.

Olorun mo wipe ati se ohun ibi, ti ope ni ese. Iku ni ere ese, sugbon Olorun feran re tobe ge tofi omo re kan soso, Jesu, ranse lati ku lori igi agbelebu ki osi jiya fun ese re. Jesu si pada wa si aaye osi losi ile l'orun! Bi o ba gbagbo ninu Jesu ti osi toro idariji ese re, Yi o se eyi! Yi o si wa gbe ninu re nisisiyi, iwo yio si gbe pelu re lailai.

Bi o ba gbagbo wipe otito ni eyi, so fun Olorun wipe:
Jesu mi owon, Mo gbagbo wipe ire ni Olorun, o di eniyan lati ku fun ese mi, osi wa laaye sibe. Jowo wa sinu aye mi ki osi dari ese mi jimi, ki emi ki oni aye otun nisisiyi, ati ni ojo kan ki emi kole wa pelu re titi lai. Ranmilowo lati gbo tire ati lati je omo o re. Amin.

Ka Bibeli re ki osi ba Olorun soro lojumo!
Johannu ori keta ese kerindinlogun.